# AWỌN ASỌTẸLẸ NIPA IBI KRISTI

**Numeri 24:17; Isaiah 7:14; 9:1-7; 11:1-5; Mika 5:2;**

**Jeremiah 31:15**

**ẸKỌ 103 – FUN AWỌN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ̀ a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia" (Isaiah 9:6).**

**I Amì Kan fun Araye**

1. Jesu, imọlẹ aye, ni a o tipasẹ wundia kan bí, Isaiah 7:14; Matteu 1:21, 23
2. A o bi I ni Bẹtlẹhẹmu ti Judea, Mika 5:2; Matteu 2:6; Johannu 7:42
3. A fi orukọ marun-un pe E nihin, Isaiah 9:6
4. Ẹmi Oluwa yoo ba le E, Isaiah 11:2; 61:1; Matteu 3:16; Johannu 1:32
5. Oun yoo fi ododo ṣe idajọ, Isaiah 11:3, 4; Ifihan 19:11

**II Imọlẹ Nla Kan**

6. Nitori ẹ̀ṣẹ, okunkun bo gbogbo ilẹ, Isaiah 9:1; 2 Awọn Ọba 17:6, 7
7. Awọn eniyan ti o jokoo ni okunkun ri imọlẹ nla, Isaiah 9:2; Matteu 4:16; Efesu 5:8
8. Bi a ba gba Ihinrere, o maa n bọ́ ajaga ẹ̀ṣẹ, o si n fi ayọ̀ kún ọkàn, Isaiah 9:3-5; Awọn Onidajọ 7:22
9. Ọmọ ti a o bi yoo jokoo lori itẹ Dafidi, ijọba Rẹ ki yoo si nipẹkun, Isaiah 9:7; Daniẹli 2:44; Luku 1:32

**III Iràwọ̀ Kan lati inu Jakọbu Wá**

10. Ọpa-alade kan yoo jade lati inu Israẹli yoo si pa awọn eniyan buburu run, Numeri 24:17; Gẹnẹsisi 49:10
11. Eekàn kan yoo jade lati inu kukute Jesse wá, Isaiah 11:1, 4, 10; Iṣe Awọn Aposteli 13:22, 23
12. A gbọ́ ẹkún ati ohunrere ẹkún ni Rama, Jeremiah 31:15; Matteu 2:17, 18

## ALAYE

### Aileyipada ni Ọrọ Ọlọrun

"Li àtetekọṣe li Ọ̀rọ wà, Ọ̀rọ si wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si li Ọ̀rọ na" Ko si iyipada tabi ojiji ayida ninu Ọrọ Ọlọrun nitori o ti wà ni àtetekọṣe, on paapaa ni Ọlọrun. Bawo ni ileri Ọlọrun ti ṣe iyebiye fun wa pọ to, nitori awa mọ pe Oun yoo mu ileri Rẹ ṣẹ dandan. Ko si si ibi ti otitọ ọrọ yii gbe fi ẹsẹ mulẹ ju lọ bi ti awọn asọtẹlẹ nipa ibi Jesu. Lati igba iṣẹda ayé ati iṣubu eniyan ninu Ọgbà Edẹni titi de igba ti Ọlọrun ṣe irapada eniyan, a ri ọpọ asọtẹlẹ kaakiri ni Ọrọ Ọlọrun ti o tọka si Messiah, Olurapada gbogbo aye. Lati inu Gẹnẹsisi de opin Majẹmu Laelae titi di akoko imuṣẹ, ni a n ri asọtẹlẹ wọnyii. O mu ki a damuso pe, "Aileyipada ni Ọrọ Ọlọrun!"

### Bẹtlẹhẹmu Ti O Rẹlẹ

"Ati iwọ Bẹtlẹhẹmu Efrata; bi iwọ ti jẹ kekere lãrin awọn ẹgbẹgbẹ̀run Juda, ninu rẹ ni ẹniti yio jẹ olori ni Israẹli yio ti jade tọ̀ mi wá; ijade lọ rẹ̀ si jẹ lati igbãni, lati aiyeraiye" (Mika 5:2). Bẹtlẹhẹmu ti o rẹlẹ! Sibẹ nibẹ ni a o gbe bi Olugbala gbogbo araye. A ti sọ asọtẹlẹ yii ni ẹẹdẹgbẹrin (700) ọdun ṣiwaju ibi Kristi. Lai si aniani, ni awọn ọdun ti o tẹle asọtẹlẹ yii, ọpọlọpọ ẹlẹgan ni ko gba asọtẹlẹ yii gbọ, wọn sọ pe wọn ti gbọ asọtẹlẹ yii nigba pupọ ṣugbọn sibẹ ko ti i ṣẹ; gẹgẹ bi a ti i maa gbọ ti awọn eniyan n sọ lode oni pe wọn ti n gbọ nipa ipadabọ Jesu lati igba ewe wọn ṣugbọn sibẹ ko ti i pada. Ṣugbọn awọn ọmọ Ọlọrun gba ileri yii gbọ́ wọn si n reti ipadabọ Olugbala lai pẹ. Ọlọrun Ọrun ati aye yan ibujẹ ẹran ṣe ibi ti a o gbe bi Jesu oninututu ati onirẹlẹ.

O yan ilu kekere Bẹtlẹhẹmu gẹgẹ bi ibi ti a o gbe bi I. O yan ilu Nasarẹti ti ko ni laari lati lo igba ewe Rẹ, O n fi han gbogbo eniyan pe bi o ti wu ki a talaka tabi ki a rẹlẹ to, bi o ti wu ki a jẹ alainilaari to ninu ayé yii, Oluwa Ogo la gbogbo rẹ̀ já lati ra wa pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa ki a le ni ile kan ni oke Ọrun. Anfaani wo ni o to bayii, ani lati jẹ ọkan ninu awọn ọmọ kekere lọwọ Ọlọrun ati ajumọjogun pẹlu Kristi!

### Irawọ Kan lati inu Jakọbu

Nigba ti Balaki bẹ Balaamu lọ́wẹ̀ lati fi Israẹli bú, Ọlọrun sọ ifibu naa di ibukun, Balaamu si ri Irawọ kan ninu ẹmi lati inu Jakọbu ati Ọpá alade kan ti o dide ni Israẹli (Numeri 24:17). Egbeje ọdun (1400) lẹyin eyi, awọn amoye lati Ila-oorun ri irawọ kan ti o fara han ninu awọsanma. O dabi ẹni pe wọn mọ̀ lẹsẹkẹsẹ pe a bi Ọba kan, wọn si mu ọna ajo ti o jìn pọ̀n lọ si Jerusalẹmu lati lọ juba Ọba ti a ṣẹṣẹ bi naa.

A le ro pe iran Abrahamu ni awọn amoye wọnyii i ṣe. Lai si aniani ijolootọ Abrahamu ko fi awọn iran rẹ̀ silẹ lati ọdun wọnyii wá titi Ọba yii fi dé nikẹyin. Lẹsẹ kan naa wọn mọ irawọ naa wọn si gbagbọ pe imuṣẹ ileri naa ni yii. Wọn si mu ohun kan ṣe nipa rẹ. Wọn mura wọn si mu ọna ajo ti o jin naa pọ̀n lati lọ ri Ọba naa tikara wọn

Kaakiri gbogbo agbaye lonii ni awọn eniyan gbagbọ pe awọn ileri wọnni ti yoo ṣiwaju ipadabọ Ọba Ologo yii lẹẹkeji ti bẹrẹ si ṣẹ. Ṣugbọn eniyan meloo ni o n mura silẹ gẹgẹ bi Bibeli ti paṣẹ pe a ni lati ṣe ti a ba fẹ ri Ọba yii ninu ẹwa Rẹ.

Ko si ọkan ninu gbogbo awọn ileri rere Ọlọrun nipa akọwa Olooótọ ati Ẹni Mimọ yii ti ko ṣẹ, bakan naa ni o dá wa loju pe ko si eyikeyi ninu awọn ileri wọnni ti ki yoo ṣẹ ti o sọ nipa bibọ Rẹ̀ lẹẹkeji lati di ayinlogo ninu awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ ati ẹni iyanu ninu gbogbo awọn ti o gbagbọ (2 Tẹssalonika 1:10).

**Lati inu Wundia**

Lati igba ti aye ti ṣẹ̀ ni Ọlọrun ti n ṣe iṣẹ iyanu ki awọn eniyan le ni igbagbọ ninu agbara ati ọgbọn Rẹ awamaridi. O n ṣe ohun ti ẹda kan ko le ṣe. Nigba kan, Jesu sọ fun awọn eniyan pe, "Ẹ gbà mi gbọ́ nitori awọn iṣẹ na pãpã." Nigba kan Oluwa fẹ fun Ahasi, Ọba Juda, ni amì kan. O jẹ ọba buburu ṣugbọn sibẹ Ọlọrun foju anu han fun awọn ti o wà ninu ijọba rẹ̀. Ahasi, ẹlẹtan ti o fara han bi olufọkansin, kọ ami ti Ọlọrun ni ki o beere. Ṣugbọn sibẹ Ọlọrun pinnu lati fi ami kan hàn fún un. "Kiyesi i, Wundia kan yio loyun, yio si bi ọmọkunrin kan, yio si pe orukọ rẹ ni Immanueli."

Boya Ahasi dabi ọpọ eniyan lonii ti ko ni igbagbọ ninu iṣẹ iyanu. Ihinrere ti Matteu ati ti Luku sọ fun ni pe a bi Jesu lati inu wundia; ṣugbọn awọn onigbagbọ igbalode, awọn ti o pọ ju ninu awọn ile-ẹsin ti o wà ni orilẹ-ède wa lode oni, sọ gbangba pe awọn ko gbagbọ pe a bi Jesu lati inu wundia. Ijẹwọ Igbagbọ ti awọn Apọsteli ti ọpọlọpọ ijọ ti n lo fun dun pupọ ti wọn si pọnle gidigidi gẹgẹ bi akopọ kukuru gbogbo ẹkọ inu Iwe Mimọ́, ti di ohun ti awọn onigbagbọ igbalode fi ọwọ ró si ẹgbẹ kan. Ninu ijẹwọ igbagbọ yii, a sọ fun ni dajudaju pe a loyun Jesu lati ọwọ Ẹmi Mimọ́ wa, a si bi I lati inu Maria wundia. Bawo ni o ti rọrun to fun ẹnikẹni ti a bi nipa ti ẹmi lati gba gbogbo Ọrọ Ọlọrun gbọ́!

**Imọlẹ Nla**

Isaiah sọ asọtẹlẹ nipa ilẹ Sẹbuloni ati Naftali pe, "Awọn enia ti nrin li okùnkun ri imọlẹ nla: awọn ti ngbe ilẹ ojiji ikú, lara wọn ni imọlẹ mọ́ si."

Ni atetekọṣe nigba ti okunkun bo ilẹ, Oluwa da oorun, oṣupa ati awọn irawọ lati tan imọlẹ fun araye. Nigba ti ẹṣẹ wọ inu aye ti o si fi aye sinu okunkun ti ẹmi, Oluwa bẹrẹ si fi hàn nipa awọn wolii Rẹ pe imọlẹ nla ti o tobi ju lọ yoo tàn sinu ayé yii; imọlẹ ti yoo mọlẹ si gbogbo eniyan.

Nigba ti Josẹfu ati Maria gbe Jesu lọ si Tẹmpili lati rubọ gẹgẹ bi Ofin Mose, Simeoni, ẹni iwa-bi-Ọlọrun nì, rí Jesu, o si gbe Ọmọ- ọwọ naa lọwọ rẹ̀ o si fi ibukun fun Ọlọrun pe, "Oluwa, nigbayi li o to jọwọ ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ lọ li alafia, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ: nitoriti oju mi ti ri igbala rẹ na, ti iwọ ti pèse silẹ niwaju enia gbogbo; imọlẹ lati mọ́ si awọn Keferi, ati ogo Israẹli enia rẹ" (Luku 2:25-35).

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni ibi ileri ekinni nipa Oludande gbé wà ninu Bibeli?
2. Sọ gbogbo orukọ ti a o fi pe Jesu.
3. Ilu wo ni a sọ ninu asọtẹlẹ pe a o bi Jesu, ta ni o si sọ asọtẹlẹ yii?
4. Ki ni amì ti Oluwa fi funni nipa ibi Jesu?
5. Asọtẹlẹ meloo nipa ibi Jesu ni o ti ṣẹ?
6. Ta ni sọtẹlẹ pe Irawọ kan yoo jade lati inu Jakọbu?
7. Ta ni sọtẹlẹ pe Ọpa Alade kan yoo ti inu kukute Jesse jade?
8. Ta ni Irawọ, Ọpa-Alade ati Ẹka ni n tọka si?